Ẹniti ó bá pade Ọlọhun ni ẹniti kò mú orogun kankan pẹlu Rẹ, onitọhun yoo wọ Alujanna, ṣugbọn ẹniti ó bá pade Rẹ ni ẹniti ó mú orogun pẹlu Rẹ, onitọhun yoo wọ Ina

Lati ọdọ Jabir ọmọ Abdullah - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - ó sọ pé: Mo gbọ Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ti n sọ pe: "Ẹniti ó bá pade Ọlọhun ni ẹniti kò mú orogun kankan pẹlu Rẹ, onitọhun yoo wọ Alujanna, ṣugbọn ẹniti ó bá pade Rẹ ni ẹniti ó mú orogun pẹlu Rẹ, onitọhun yoo wọ Ina".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n ṣe alaye pé ẹnikẹni tí ó bá kú, tí kò mu orogun kankan pẹlu Ọlọhun, Alujanna ni ibupadasi rẹ kódà bí wọn bá jẹ ẹ niya nitori apakan ninu awọn ẹṣẹ rẹ, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba ku, ni ẹniti n mu orogun pẹlu Ọlọhun, onitọhun yoo wọ inu Ina gbere.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3418